Ẹnikan ninu yin ko gbọ ku ayaafi ki o ni àbá daada si Ọlọhun

Lati ọdọ Jaabir - ki Ọlọhun yọnu si i - o sọ pé: mo gbọ tí Anọbi - ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ máa ba a - sọ ni ọdun mẹta síwaju koto fi ayé silẹ báyi pé: "Ẹnikan ninu yin ko gbọ ku ayaafi ki o ni àbá daada si Ọlọhun".

[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Anọbi (kí ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ máa ba a) gba musulumi níyànjú lati má kùú ayaafi ki o ni àbá daada si Ọlọhun pẹlu ki o fi abala inireti sọdọ Ọlọhun leke nígbàtí nba pọka iku lọwọ n'ireti pe Ọlọhun Yóò ṣekẹ rẹ yóò ṣe amojukuro fún un; nitoripe ifoya ni nkan ti wọn beere fún ki a le ri iṣẹ se daada, ìṣesí un kii se iṣesí iṣẹ ṣiṣe, nkan ti wọn fẹ nibẹ ni ki ireti borí.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/3779